# A RỌ ỌBA LOYE, A SI RẸ IGBERAGA RẸ̀ SILẸ
## Daniẹli 4:1-37
## ẸKỌ 421 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Nipa ọ̀rọ lati ọdọ awọn oluṣọ li ọ̀ran yi, ati aṣẹ nipa ọ̀rọ awọn ẹni mimọ́ nì; nitori ki awọn alàye ki o le mọ̀ pe Ọga–ogo li o nṣe olori ni ijọba enia, on a si fi fun ẹnikẹni ti o wu u" (Daniẹli 4:17).**

**I Àlá Ọba**

1 Nebukadnessari jẹri pe ainipẹkun ni Ijọba Ọlọrun, Daniẹli 4:1-3

2 Ọba lá àlá, o ri igi nla ti a gé lulẹ̀, Daniẹli 4:4-17; Orin Dafidi 37:35, 36

**II Itumọ ati Ikilọ**

1 Awọn ọlọgbọn Babeli kò le tumọ àlá ọba, Daniẹli 4:18, 6, 7; 2:2-13

2 Daniẹli tumọ àlá naa, Daniẹli 4:19-26; 2:36-45

3 Daniẹli gba ọba ni imọran lati fiyesi ikilọ àlá naa ati lati fi ododo já ẹ̀ṣẹ rẹ̀ kuro, Daniẹli 4:27; Isaiah 58:1; Jeremiah 26:3; Esekiẹli 3:18; Matteu 27:19; Heberu 12:25

**III Imuṣẹ**

1 Lẹyin oṣu mejila ti o kun fun igberaga ati kikọ̀ aanu Ọlọrun, a rọ Nebukadnessari loyè, Daniẹli 4:28-32; 5:20; 2 Kronika 26:16; 32:25; Isaiah 14:12-15

2 Nigba ti a le e jade kuro ninu aafin rẹ̀, ọba n gbé laaarin igbẹ́ bi ẹranko, Daniẹli 4:33; 5:21; Orin Dafidi 32:9

3 Lẹyin ti igba meje ti kọja lori Nebukadnessari, o yipada si Ọlọrun, oye rẹ̀ si tọ ọ wá, Daniẹli 4:34; Iṣe Awọn Apọsteli 8:22

4 A dá ijọba Nebukadnessari pada fun un, nigba ti o gbà pé Ọlọrun ni n ṣakoso ni Ọrun ati ni ayé, Daniẹli 4:35, 36, 17, 25, 32

5 Nebukadnessari sọ ẹri rẹ̀, o si ṣe ikilọ nipa igberaga, Daniẹli 4:37, 1-3; Owe 16:18; 29:23; 1 Johannu 2:16; Ifihan 3:17

ALAYE

Ninu ẹkọ wa atẹyinwa, a kà ninu ori keji Daniẹli bi Ọlọrun ti fi hàn fun Nebukadnessari ninu àlá pe oun gan an ni ere naa ti ori rẹ̀ jẹ wura ti o n tọkasi gbogbo ijọba ayé. Ọba Ọrun fun un ni ijọba Babiloni ati gbogbo agbára, ipá ati ogo ijọba naa, o si pe e ni ọba awọn ọba. Njẹ ẹni kan wà ti kò ti i di atunbi, ti Ọlọrun bukun fun, ti O gbé ga, ti O si sọ di alaasiki ti ki yoo gba gbogbo ọla naa fun ara rẹ̀, ti ki yoo si gbagbe pe Ọlọrun ni O fun oun ni gbogbo nnkan wọnyii? Nebukadnessari kò ti i kọgbọn, kò si ti i gbà pe "Ọga-ogo ni iṣe olori ninu ijọba enia."

**Asọtẹlẹ ati Ikilọ fun Ọba**

Nebukadnessari ti ṣe aṣeyọri ninu eto ilu, o si ti ja ajaṣẹgun ninu ogun. O ti tẹ ori gbogbo awọn ọta rẹ̀ ba; ohun gbogbo ni o si n lọ deedee fun un ni gbogbo ijọba rẹ̀. O sọ ilu Babiloni di ọ̀kan ninu awon ohun iyanu ayé. Gbogbo ohun ti o si fi ọwọ rẹ̀ le ni o yọri si rere. Kò si ohun ti o kù mọ́ lati tẹ́ ọkanjuwa rẹ̀ lọrùn gẹgẹ bi ẹda tabi lati fi kun ogo rẹ̀ gẹgẹ bi ọba. Bi o si ti n sinmi ninu ile rẹ̀ ti o si n gbilẹ ni aafin rẹ̀, o lá àlá kan. Àlá yii ti a ṣe apejuwe rẹ̀ yekeyeke ninu ori ẹkọ wa ni ọba ranti ti o si fi ẹnu ara rẹ̀ sọ ni kinnikinni. Ṣugbọn ọba naa kò mọ̀ itumọ rẹ̀. O yẹ ki o hàn lati inu ala naa pe ikilọ nla ni eyi fun ọba nitori igberaga ati wiwá ogo ara ẹni, ati pe Ọlọrun yoo rán irẹsilẹ ni kánkán si awọn wọnni ti wọn n fi ogo fun ara wọn lori awọn nnkan ti wọn ti ṣe tabi ti wọn n gbadun. Kò ṣe anfaani lati tun sọ pe, ala yii ati ohun ti o le tumọ si ba ọba lẹru.

Lẹyin ti awọn ọlọgbọn Babeli ti kuna lati tumọ ala naa, Daniẹli wá siwaju ọba. Ọba naa sọ ẹri ti o ya ni lẹnu nipa ijolootọ Daniẹli, wolii Ọlọrun, o si sọ ala naa fun un. Fun wakati kan ti Daniẹli fi duro

niwaju ọba, kò le sọrọ. Irò inu Daniẹli daamu rẹ̀, boya nitori itumọ ala yii yatọ pupọ si ti ala iṣaaju. Lati duro niwaju ọba ti okiki rẹ̀ kàn jake-jado gbogbo ayé ki a maa sọ aiṣedeedee rẹ̀ fun un yatọ pupọ si pe ki a duro niwaju rẹ̀ lati sọ fun un pe ọba alagbara ni oun ati ori wura ninu eto iṣakoso agbaye. Ṣugbọn nipa ikiya ti ọba fun Daniẹli, o wi fun ọba pe oun ni igi naa ti o dagba ti o si di alagbara, "nitori titobi rẹ̀ ga o si kan ọrun, agbara ijọba rẹ si de opin aiye." Ṣugbọn gẹgẹ bi ala naa ti sọ tẹlẹ̀, a o le e kuro laaarin awọn eniyan, yoo si ni ibugbe rẹ̀ laaarin awọn ẹranko igbẹ, yoo si jẹ koriko bi maluu, ìrì ọrun yoo si sẹ si i lara titi igba meje yoo fi kọja lori rẹ̀. Nigba naa ni Daniẹli, ni ijolootọ si Ọlọrun rẹ̀ ati lai ka ewu ẹmi rẹ̀ si gba ọba ni imọran lati fi ododo já ẹ̀ṣẹ rẹ̀ kuro, ati aiṣedeedee rẹ̀ nipa fifi aanu hàn fun awọn talaka. Wo iyatọ ti i ba ti wà ninu abayọrisi ala yii bi o ba ṣe pe Nebukadnesari ọba fetisilẹ si ikilọ naa!

**Ẹ̀ṣẹ Ọba**

A le ni ireti pe iru asọtẹlẹ ati ikilọ ti o mu ni lara bayii ki yoo ṣai yọri si ohun ti a n fẹ́, ṣugbọn kò si ohun ti o kún fun ọtẹ ati itanjẹ tó ọkàn oṣi ati ibajẹ ẹda eniyan. Lai si aniani ipinnu Nebukadnessari ni lati jẹ anfaani imọran ti a fun un ni kikun. O ni igbẹkẹle ti o duro ninu ọgbọ́n ati imisi wolii naa. O ni idi ti o fi gbọdọ gba gbogbo ọrọ ti a sọ fun un bi otitọ lati ọdọ Ọlọrun wá, bẹẹ si ni pẹlu, kò si ninu iwa ọba yii lati fi oju tininrin iṣẹ ti a rán si i lati ọdọ Ọga-Ogo Ẹni ti oun ti ri iṣẹ ami ati iṣẹ iyanu Rẹ̀. Ṣugbọn o ṣoro fun awọn ọlọrọ ati awọn alagbara laaarin ogo ati apọnle ti wọn n ri gbà lati jẹ́ oloootọ si ohun gbogbo ti wọn mọ̀ ti wọn si kà si ojuṣe wọn. Olugbala ati awọn Apọsteli Rẹ̀ ti sọ ti iṣoro nla ti yoo wà fun iru awọn eniyan bẹẹ lati wọ Ijọba Ọrun, Nebukadnessari paapaa kò bọ́ ninu eyi. Njẹ alaiwa-bi-Ọlọrun kan wà nibi iṣẹ ijọba ti a le gbé agbára ati ogo bẹẹ lé lọwọ ti ki yoo ṣi i lò, ti igberaga ọkàn rẹ̀ ki yoo ga kọja ọrun?

O ṣe e ṣe ki ọba yii ki o ronu fun igba pipẹ nipa ala yii, ati lai si aniani yoo maa rin pẹlu iṣọra nitori ọrọ naa. Nikẹyin, lẹyin oṣu mejila, o n rin kiri lori ibi giga ni aafin rẹ̀ ti o kún fun ọpọlọpọ odi ati ile-iṣọ ti a ṣe lẹwa. Ni ayika ati ni isalẹ ni ọba n wo ilu Babeli pẹlu ọpọ ẹwà rẹ̀ ati awọn ogiri giga ti o ni ọgọrun ẹnu-bode nlá nlà. Bi Nebukadnessari ti n wo awọn nnkan nlá nlà ti ọwọ rẹ̀ ti ṣe, o fi igberaga tọka si ara rẹ̀ ati si ọgbọ́n ara rẹ̀, ṣugbọn o ṣá Ọlọrun ayeraye tì, Ẹni ti, lai si Rẹ̀ ti oun kò ni laari ju akuṣẹ alagbe lọ. O wo, ọkàn rẹ̀ si fẹ wọn, ṣugbọn o gbagbe nipa ala naa, o si wi pe: "Koṣepe eyi ni Babeli nla, ti emi ti fi lile agbara mi kọ́ ni ile ijọba, ati fun ogo ọlanla mi?"

O ti gbọ́ ọrọ "oluṣọ" ọrun, Daniẹli si ti ṣe atunwi ọrọ naa pe, iṣẹ rẹ̀ ni, gẹgẹ bi o ti jẹ́ ti gbogbo eniyan lati mọ̀ pe Ọga-Ogo ni i ṣe olori ni ijọba eniyan, Oun a si fi i fun ẹnikẹni ti o wu u; ṣugbọn ni akoko idunnu ati ayọ lori ohun gbogbo ti o ti ṣe, Nebukadnessri gbagbe gbogbo eyi, o si bẹrẹ si i gba ogo fun ara rẹ̀ lori wọn. Nipa bayii o fi ọkàn rẹ̀ fun igberaga, o si sọrọ igberaga jade, eyi ti i ṣe ẹ̀ṣẹ ti o rọrun to o rọ̀gba yi ọkunrin yii -- ẹ̀ṣẹ ti o rọrun ti o yi gbogbo awọn eniyan ti o wà ni ipo giga ninu ayé ká – eyi ti o dé gongo nigba ti Nebukadnessari n rin, ti o si n sọrọ laaarin awọn ile-iṣọ ati odi ti o yi aafin rẹ̀ ologo ká.

**Ijiya Ọba**

Ọlọrun ti fi aafo oṣu mejila tọ̀tọ̀ fun ọba yii lati ṣe aṣaro ati lati ronupiwada kuro ninu igberaga ati ogo asán rẹ̀. Ijiya dé kankan nigba ti akoko Oluwa dé. Bi ọ̀rọ naa si ti wà lẹnu ọba, ohùn kan fọ̀ lati Ọrun wá, pe, "A gba ijọba kuro lọwọ rẹ" – eyi ti ọba ti ri ni oju àlá ti wolii oloootọ nì ti sọ itumọ rẹ̀ wá ṣẹ nikẹyin. O dabi ẹni pe iṣe were kan ni o kọlu ọba eyi ti o du u ni oye rẹ̀ ti oun paapaa bẹrẹ si ronu pe ẹranko kan ni oun. Eyi le ri bẹẹ nitori ni itọkasi iwosàn rẹ̀, o wi bayii pe: "oye mi si pada tọ̀ mi wá." Sibẹ a kò le rò pe ipọnju ara lasan ni eyi, nitori lati ọdọ Ọlọrun ni eyi ti wá gẹgẹ bi abayọrisi ẹ̀ṣẹ ati igberaga. O ti fi ogo ti kò tọ́ fun ọgbọ́n ara rẹ̀. Ọlọrun si ti rẹ ọgbọ́n naa silẹ to bẹẹ ti kò sàn ju maluu ti o n jẹ koriko lọ; o ya ẹranko to bẹẹ ti ẹnikẹni ko lero pe o ti jẹ́ eniyan lẹẹkan ri. Apejuwe Nebukadnessari ni iru ipo yii fi ipọnju nlá nlà ti o le dé bá eniyan, ki a má tilẹ sọ ti iru ẹni ti o wà ni ipo ọba nla bi Nebukadnessari. Dajudaju, ohun ẹ̀rù ni lati ṣubu si ọwọ́ Ọlọrun Olodumare.

**Iwosàn Ọba ati Idapada Sori Oyè**

Igba meje, boya ọdun meje ti kọja lori ọba ni iru ipo yii, ṣugbọn "li opin igba na, Emi Nebukadnessari si gbé oju mi soke ọrun." Igbé-oju si oke ọrun nì jẹ́ lati ọdọ ẹni ti o ri wahala nla ti o si n fi tẹduntẹdun bẹbẹ fun aanu ati iranlọwọ lati ọdọ Ẹni ti o ti n wá. Ìwò irẹlẹ ati ọ̀wọ ni eyi fun Ọlọrun Ọrun ati iwò adura fun iyọ́nú: iwo ti o mú alaafia wá ni. Ọba naa wi pe: "Oye mi si pada tọ̀ mi wá, emi si fi ibukún fun Ọga-Ogo, mo yin, mo si fi ọla fun ẹniti o wà titi lailai, ẹniti agbara ijọba rẹ̀ jẹ ijọba ainipẹkun, agbara ati ijọba rẹ̀ lati irandiran: gbogbo awọn araiye li a si kà si bi ohun asan, on a si ma ṣe gẹgẹ bi o ti wù u ninu ogun ọrun, ati larin awọn araiye: kò si si ẹniti idá ọwọ rẹ̀ duro tabi ẹniti iwi fun u pe, Kini iwọ nṣe ni?"

Idajọ kikoro ti de ba a, ṣugbọn o ṣiṣẹ ribiribi ni igbesi ayé rẹ̀. O rẹ igberaga rẹ̀ silẹ. O jẹ ki o fi tọkantọkan mọ Ọlọrun otitọ. O jẹ ki o le sa gbogbo ipá rẹ̀ lati fi ọla ati ogo fun Jehofa. O mu gbogbo itiju ati ìyemeji lati jẹwọ ẹ̀ṣẹ kuro ninu ọkàn rẹ̀, ati ododo ti o wà ninu iya ti oun ti jẹ nipa dida ẹ̀ṣẹ. O sọ ọ di ẹni ti o n fi itẹriba búrúbúrú sin Ọlọrun ati ajihinrere ọba ti Ọlọrun otitọ. O ti kọ́ pe Ọrun ni i ṣe olori, ifẹ ọkan rẹ̀ nisisiyii gẹgẹ bi ọba ni pe ki gbogbo eniyan, orilẹ ati ède ni gbogbo agbaye ki o mọ̀ eyi lai jẹ pe wọn fi wahala ati ibanujẹ mọ ọn gẹgẹ bi o ti ri fun oun.

Lẹyin ti gbogbo ipọnju nla yii ti de ba a, aanu ati iṣeun Ọlọrun ni o jẹ ki o ṣe e ṣe pe ki o tun le pada sori oyè rẹ̀ lai jẹ pe ẹlomiran ti gba a lọwọ rẹ̀. O le jẹ pe Daniẹli ati awọn ọmọ Heberu mẹta ti a ti gbé ga ninu ijọba naa ni Ọlọrun lò lati di ipo naa mú de ọba. Wọn mọ̀ pe fun igba diẹ ni ipọnju yii ati pe oun yoo tun pada bọ̀ sipo. Nitori naa ọba sọ ẹri rẹ̀ bayii pe, nigba ti akoko ipọnju oun wá si ipari, awọn ijoye ati awọn igbimọ oun ṣafẹri oun, a fi ẹsẹ oun mulẹ ninu ijọba, oun si ni ọlanla agbara si i.

Bi a ba mọ ibawi Ọlọrun ti a si gba a, eyi a maa fi ọkàn wa balẹ fun ojurere Ọlọrun.

**AWỌN IBEERE**

1 Ni ọrọ ara rẹ, ṣe apejuwe àlá ti Nebukadnessari lá.

2 Awọn ọrọ iyin wo ni ọba sọ nipa ọgbọ́n ati òye Daniẹli?

3 Ki ni ṣe ti ọba ṣe ni igbẹkẹle to bẹẹ ninu òye Daniẹli?

4 Lẹyin ti Daniẹli ti tumọ àlá naa, ki ni ohun ti o tún sọ fun ọba pẹlu?

5 Ki ni le mu ki àlá naa ki o má ṣẹ?

6 Ki ni ọba naa n wi nigba ti Oluwa jẹ ki ohun ti ala naa tumọ si ṣẹ?

7 Iyipada wo ni imuṣẹ ala naa mú wá ninu igbesi-ayé ọba nikẹyin?